# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 853 LAGOS SATURDAY JANUARY 12 — JANUARY 18 1963 KOBỌ MEJI (2D)


# Here! Lesi Ma J o b a Alake Ilu Egba?

## Awon Omo Oba Ti Nfenia Ranse

ABẸOKUTA— Hẹre! Ọmọ lesi ma j' ọ b a Alake? Gbolohun ọrọ yi ti yika igun mẹrin ilu Ẹgba loko ati nile lati ọjọ ti a ti gbọ wipe Alaiyeluwa Ọba Ademọla Keji ti waja, gbogbo awọn Ologboni ilu Ẹgba a ti awọn Ọmọba si ti nfori kori lati jiroro ẹniti o tọ si lati fi jẹ ọba Alake miran.

Onirohin wa ni ninu nwọn nṣe eto tani yio joye yi lọwọ, awọn Ologboni gẹgẹbi aṣa ilu Ẹgba ti y a n awọn Oloye pataki meji gẹgẹbi "Adele-Ọba" si Afin Ake, awọn na ni Oloyede Adeṣina, Oluwo Ijeun ati Oloye Adekunle Coker, Oluwo Iporo.

Awọn iran ọba mẹta pataki ni nwọn ti fi orukọ ranṣẹ si awọn afọbajẹ. Awọn orukọ na ni Ọmọ Ọba Samuel Ade. Gbadebọ ati ọmọ oba Adebọ Okunkẹnu (awọn iran Larun) Ọgbẹni Abiọla Jacob ira. (Okikilu) Olu. Luwaji (iran Ọba Luwaji), Adebọ Okunkẹnu (iran Ọba Okunkẹnu).

Awọn ti a tun gbọ wipe nwọn fi iwe ti won na ranṣẹ si awọn afọbajẹ lana ni Lọ a Ayọ Sholankẹ, ọmọ Ologbe "Funf atẹyẹṣu" l'Ake ati Ọmọba Oripẹde. Ayiluka "Eleti Ọfẹ" yio ma sọ iyọku fun a lọsẹ ti mbọ.


## LAGOS RACE CLUB

THE ANNUAL GENERAL MEETING will be held in J. K. Randle's Memorial Hall, Tafawa Balewa Street, Onikan Road, Lagos on Thursday 31st January, 1963 at 5 p.m. ONLY MEMBERS OF THE CLUB WILL BE ADMITTED AND MEMBERSHIP BADGES will be inspected at the gate.

AGENDA:

1. Chairman's Address
2. Accounts
3. Election of Chairman
4. Election of Committee Members.

RULE 11- "The Management of the Club shall be vested in a Committee of 18 in addition to the Chairman who shall be elected annually. Provided that no one shall be eligible for election at a General Meting as a member of the Committeee unless his name, duly proposed and seconded, has been handed to the Secretary at least 14 clear days before the General Meeting in question and the list of such nominations shall be available for inspection at the Secretary's" Office 7 days before the Meeting.

RULE 12 — Any Full Member w i s h i n g to move any resolution at any Annual General Meeting shall give notice in writing to the Secretary at least three days before the meeting".


## Obinrin Kan Loyun Meji Lotolo Lekan

DENMARK—Oju a ri nkan to ninu ile aiye; obinrin kan ti awọn olotu ijọba ilu Denmark nibi kọ lati da orukọ rẹ fun awọn oniwe irohin ni a gbọ wipe o bi ọmọ meji (ti nwọn ki ṣe ibeji) larin oṣu kan, kiṣe lọjọ kanna.

Awọn oniṣegun (dokita) Oyinbo ti obinrin na bi sọdọ wọn ni ọrọ na ṣe awọn ni kayefi nitoripe awọn ko gbọ iru rẹ ri ki obinrin loyun ọmọ meji lọtọtọ.

Nwọn ni, o ni lati jẹ wipe lẹhinti o ti loyun ti akọkọ tan ni ile ọmọ rẹ tun si s i l ẹ f u n omiran, Ọkan ninu awọn ọmọ na ti jalaisi nisisiyi ṣugbọn nkankan ko ṣe iya wọn pẹlu ọkan ninu awọn ọmọ na ti o wa nilẹ.

## Awon Omo Iya Marun Je Oiu Nwon Ku Bamu-Bamu

AGBADO (Leti Ilesha) - Anu abiyamọ ṣe awọn ara abule ti nwọn npe ni Agbado nigbati nwọn ri awọn ọmọ iya kanna ti marun ku silẹ ninu ile wọn.

Onirohin wa ni ọmọ mẹfa ni iya awọn ọmọ na ti njẹ Abikẹ Ajagbe bi fun ọkọ rẹ Adeagbo Ajagbe. Ni ọjọ ti nkan yi ṣẹlẹ, awọn obi awọn ọmọ nwọnyi ko si nile, nwọn ba awọn aladugbo wọn lọ si i b i igbeyawo ni arọko kan ṣugbọn fi owo onjẹ silẹ fun wọn.

Nigbati o di asalẹ ni eyi ti o jẹ agba ninu awọn ọmọ na pe awọn aburo rẹ pe ki awọn lọ ja efọ ni oko lati fi se'bẹ; bi nwọn ti npada ti oko bọ ni nwọn ya ayaba lati tu diẹ ninu awọn ola kan ti nwọn ri lẹba ọna, nwọn si se mọ ọbẹ ti nwọn fi jẹ iyan. Ọkan ninu wọn, Oladṣu, ti o lọ ba awọn ẹgbẹ rẹ t'ayo, ti ko tọla ninu ọbẹ na ni ko lọ sorun lẹpapandodo.

(Woyoku loju ewe Kẹjọ)



# E Ma Gbadun

Aworan yi ni ti awon omoge iiu Gesi marun ti nwon wo aso ti o yato si aso–isere nigbati nwon nlo ibi ere agbaiye kan ti se laipe yi ni iiu Oyinbo. Oruko awon omoge na ni Linda Knowles, Ann Packer, Daphne Arden, Betty Moore ati Dorothy Hayman.




## "IGBEYAWO NA"

Barclays Bank ti se awon aworan kan na eyiti idanilaraya... lati ... boya iwo papa ti ... tele. Aworan ti anpe ni "IGBEYAWO NA" jamo itan odomokunrin kan ... fe gbe arewa omidan ti anpe ni Alake n'iyawo. Sugbon baba Alake ko gba!



Mamokunrin na ti oruko ... Kwesi lo si ile okere lati ... lati ma f'owo pamo ... agbara ti mo. Nigbati o si pada, ... koko se nipe, o bere si f'owo pamo sinu banki ti Barclays. ... akoko yi, nun ... ki ... bubu ru kan ji olufe re gbe lo.



# Iwọ ha lè gbe iyawo bi? Iwọ le ṣe bẹ laipẹ lọ titi bi o ba bẹrẹ lati ma f'owo pamọ ni ọdọ Barclays nisiyi!

Latigba degba ni ki o ma f'owo pamo. ... o si ... ju re s'ile ... owo. ... okan tan Barclays nipa ... owo re, eyiti iwo yio ... pada yio si ju iye ti o fi ... lo! Lo bere ni banki ti Barclays ... nitori odo re nipa fifi ... re pamo. Awon ni yio fun ... ni imoran ati iranlowo to d arajulo.

Sugbon ... nikehin ... gbogbo ... bubuni ... iwo iye ... ni Barclays Bank. Iwo na ... bere lati ma f'owo pamo, ... igbeyawo ... owo ...!

BARCLAYS BANK D.C.O.

*Ile ise owo ... bakiri ...*

## Orin Ibile Ti Awon Egba Fi Nki Oba Alake

AKIYESI: Eleyi ni orin ibilẹ ti awọn Ẹgba ma fi nṣe ẹyẹ fun ologbe ọba Ademọla Keji nigbati o wa laiye. Ọkan ninu awọn ọmọ Ẹgba, Alufa (Rev) Ransome-Kuti ni o da orin na ni 1920.

"Ọmọ Abati" ni o da ọn loju pe orin yi na ni nwọn yio ma lo fun ọba Alake miran, sugbọn orukọ ni yio yatọ.

—OLOTU

1, Kabiesi Ọba Alake,
Ademọla Keji,
Ọmọ Erin Jogun ọia,
Ọmọ ọtẹmikan,
Kabiyesi, kabiyesi.

2, Awa ewe Abẹokuta,
Ayin 'Luwa logo,
Fun anu ati orerẹ
Si oba Ademola
A si nkọin
Ogo ! Ogo !!

3, Fi ẹbun ati ore ẹlẹ rẹ,
Tẹ Ọba wa lọrun
Ki ade ko pẹ lori rẹ.
Ki bata pẹ lẹṣe
Ki a si mọ kọrin
Kabiyesi.

# Kabiyesi Oba Alake Ademola Keji

## Adegboyega

GẸGẸBI mo ti sọ ninu itan mi ninu iwe yi ni ọsẹ ti o kọja nipa igbesi aiye Alaiyeluwa wipe ọpọlọpọ ọdun ti o fi ṣe ọdọmọde ilu Eko ni o gbe ti ṣe ṣugbọn ko nye fi igba kọkan lọ si Abẹokuta lati lọ si ọdọ aburo baba rẹ Alaiyeluwa Ọba Gbadebọ, ọmọ Ẹfunwunmi, ti o wa lori itẹ nigbana fun imọran nipa ọrọ inu.

Nitotọ gbogbo yin ni ẹ ti gbọ ti ẹ si ti mọ nisisiyi wipe nigba atijọ ilu Ẹgba na fi igba kan wa ni OMINIRA. Ominira na ko si fi ara kọ nkankan rarạ, awọn enia ti nwọn si gba ni o si ṣe gẹgẹbi akọwe jẹ awọn ti o mọ iwe gidigidi (tabi tani o le wipe bawo ni ti awọn ọmọ Ẹgba jẹ ninu awọn omọwe igbani?) nwọn ko si fi iṣẹ ọwọ wọn jafara.

## Edun

Ni gbogbo igbati Ọba wa yi wa ni Eko ni o ti fi oju si ara Ọgbẹni ti o nṣe iṣẹ tiṣa ni ile iwe kan ni Eko, ọgbẹni na ni Alufa Samuel.

Alufa Samuel jẹ olukọ agba ninu ile iwe ti a npe ni Wesleyan Boys High School (eyiti nwọn npe ni Methodist nisisiyi) nigbana, o si rin jinna ninu ẹkọ pupọ.

Nigbati nwọn gba sinu iṣẹ gẹgẹbi akọwe Ijọba ilu Ẹgba Henry Samuel ni o njẹ ki o to wa yi orukọ rẹ pada si Adegboyega Ẹdun.

Baba mi sọ fun mi wipe idi ti o fi sọ orukọ rẹ ni Adegboyega ni wipe, ni akoko ti on de ori aga gẹgẹbi akọwe-agba ilu awọn Ẹgba ni gbogbo nkan bẹrẹsi lọ dede; inu Ọba Gbadebọ ti o wa lori itẹ nigbana si dun si i. Gbogbo nkan ti Ọgbẹni Ẹdun ba sọ nigbana ni aṣẹ.

IRIN AJO ...

Nitotọ nigbati Ọgbẹni Adegboyega Ẹdun de ori aga gbogbo nkan bẹrẹsi dun yungba bi agbayun ni ilu Ẹgba l'Abẹokuta, awọn ti o nṣe owo njẹre; ọkọ reluwe ti de nigbana. Ijọbo Gẹsi ilu Eko bẹrẹsi bẹ awọn ọmọ Ẹgba wipe ki nwọn wa ba awọn ṣe iṣẹ ọkọ reluwe na.

Bi o ba fẹ ja idi ofintoto itan ti mo npa yi, ki ẹ lọ wo inu iwe atijọ awọn ọlọkọ reluwe na, ẹ o ri wipe orukọ awọn ọmọ Ẹgba ni o pọ ninu awọn ti nwọn kọ ṣe Olori-tesọn (Station-Master) ati awọn awakọ (locomotive driver). gbogbo orukọ awọn die ninu awọn ọmọ Ẹgba ti mba da ninu awọn ti wọn ṣe iṣẹ na, mo fi di ọjọ miran.

## Ilu Oyinbo

Nigbati gbogbo nkan na nlọ pẹsẹ, Gomina ilu Gẹsi ti o wa ni Eko nigbana wa fi ọrọ we ọrọ pẹlu awọn oselu Ẹgba wipe, o yẹ ki Ọba Alake igbana, Alaiyeluwa Ọba Gbadebọ wa lọ mọ ilu Oyinbo. Gomina Ọlọla igbana ni a npe ni Sir William Mac-Gregor ọmọ ilu ti a npe ni Scotland ni ilu Oyinbo.

Nigbati Alaiyeluwa Ọba Gbadebọ nlọ si ilu Oyinbo na ni iwọn nkan bi ọdun mejidinlọgọta si igba yi, o mu Ọba wa, Alaiye-Ọba Ademọla Keji ti a nsọ itan igbesi aiye rẹ yi lọwọ, o tun mu akọwe-agba Ijọba ilu Ẹgba, Adegboyega Ẹdun lọwọ pelu Ọgbẹni Richad Baale Blaize ati A. Shomoye pẹlu Ọkunrin kan ti wọn npe Adenla.

Boya orukọ baba wa ologbe Ọgbẹni Blaize le da bi eni wipe Oyinbo alawọ funfun ni ni ojẹ enyin ọkawe itan mi, rara ọmọ Ẹgba-Owu nișe pelu Ologbe Shomoye. Ologbe Blaize si jẹ ẹnikan ninu awọn olowo ilu Ẹgba nigbana.

Ko si ibi pataki pataki (Wo yoku oju ewe kẹfa)

## PAPA ERE TUNTUN



Eleyi ni aworan papa ile-ere tuntun ti nwọn ṣẹṣẹ pari ni ilu London, o si gba to ọkẹ enia awọn aworan lati joko wibẹ.

# ELETI—OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI LEJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28 Kosọkọ Street, Lagos, P O. Box 468     "ELETI—OFE" LAGOS Phone 23370

VOL XIV. No. 852 SATURDAY JAN. 5, — JAN. 11, 1962


# Ija—Ko—D'ola

AWỌN agbalagba a ma pa owe wipe "agbajọ ọwọ ni a ma fi nsọ aya, ẹnikan kọjẹ awa de" iyẹn ni esi ti awa onirohin Eleti-Ọfẹ yio fi si ọ r ọ-ẹbẹ pataki ti Gomina tuntun ti nwọn ṣẹṣẹ yan ni Ipinlẹ Ijọba Iwọ Orun, Ọlọla Joseph Ọdẹleyẹ Fadahunsi, fi bẹ awọn enia lọkunrin ati lobinrin t i nwọn w a ni Ipinlẹ na wipe ki nwọn gbagbe gbogbo nkan ruke-rudo ti o ti kọja lọ, ki nwọn wa ọna ti ola yio fi ni ilọsiwaju.

Gomina tuntuu na ṣe alaye, o ni ki a boju wẹhin, ti o ri wipe ọpọlọpọ nkan r e r e ni rogbodiyan yi ti bajẹ fun wa lati nkan bi oṣu meje sẹhin. Owo ko si ni ilu tobẹ; ọpọlọpọ awọn oṣiṣe paapa ni nwọn ti da duro lẹnu iṣẹ, aya awọn ara ilu ko ba lẹ rara.

Nitotọ ọtẹ ko ntun nkan ṣe, ọṣe ni o mba a jẹ, sugbọn Gomina wa tuntun ni on kan saara fun awọn ara Ipinlẹ Iwọ Orun fun diduro ti nwọn duro ṣinṣin, ti nwọn si pa ofin mọ, ti ija pẹlu itaja silẹ ko si larin rogbodiyan na.

Eleyi dara pupọ ṣugbọn o yẹ ki awa na kesi awọn Olotu Ijọba titun na wipe agbajọ ọwọ ni a fi nsọ aya ati pe bi igi ko ba si lẹhin ọgba wiwo ni nwo.

A gbọ wipe awọn Olotu Ijọba tuntun na ti nmura, nwọn si ti ngbaradi lati ri wipe awọn ṣe ohun ribiribi fun awọn ara ilu. Adura awa ni pe ki Ọlọrun Olodumare le jẹki apa wọn ki o kaa, nitoripe IJA KO D'ỌLA.


## NIGERIAN PORTS AUTHORITY

### INVITATION TO TENDER

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of the undermentioned scrap materials now lying on the Authority's premises, (1) at Apapa Quays, (2) at Apapa Dockyard and (3) at Port Harcourt Quays:-

APAPA

| Lot No | Description |
| --- | --- |
| 1. | Morris Oxford Traveller LD.3218 |
| 2. | " " " LD.5729 |
| 3. | Morris Van 30 cwt. LB.2372 |
| 4. | Bedford Lorry 5 ton LB. 145 |
| 5. | Morris Lorry 5 ton ... 12 |
| 6. | Morris Kit Car 10 Seater LB.2536 |
| 7. | Morris Van 10 1/2 cwt. LB.2537 |
| 8. | Ford Consul Saloon LC 5717 |
| 9. | 6 Electric Motors ) 2 Generators ) As one lot 4 Brake olenoids) |
| 10 | 1 1/2 Ton Portal Crane No. 507A. |
| 11. | 43 Lead Acid Batteries-As one lot. |
| 12. | 22 Refrigerators ) 16 Cookers ) 8 Ceilling Fans ) As one lot 4 Table Fans ) 7 Water Heaters ) |
| 13. | 5 Electric Rivet Heating Machines-As one lot |
| 14. | 101/2" Centre Lathe No. 017 |
| 15. | 8" " " No. 036 |
| 16. | 8" " " No. 034 |
| 17 | 138 No. 44 Gallon Drums ) 71 " 10 Gallon Paint, Grease and Whitewash Drums ) 480 " 5 Gallon Paint Drums ) 214 " 4 Gallon Kerosene Tins )As one lot 37 Nail Drums ) 39 Carbide Drums ) 17 No. 2 Gallon Paint Tins ) 5 " 1 Gallon White Lead Paint Tins ) |

PORT HARCOURT

| Lot No. | Description |
| --- | --- |
| 18. | One Ramsom Repier Crane No 664 |
| 19. | 7 Refrigerators - as one lot. |

2. The above items may be inspected on application to the following officers of the Authority between the hours of 8 a.m. - 12 noon and 2 p.m. - 4 p.m. not later than Wednesday 16thJanuary 1963 :-

Lots Nos. 1-12, Senior Stores Officer, Apapa Quays
Lots Nos. 13-17, Senior Stores Officer, Apapa Dockyard
Lots Nos. 18-19, Senior Stores Officers, Port Harcourt Quays.

3. A copy of the Form of Tender may be obtained from the Secretary, Nigerian Ports Authority, 216, Broad Street, Lagos, and from the Port Manager, Eastern Ports, Nigerian Ports Authority, Port Harcourt, on payment of £20 (Twenty pounds) to the Authority's Cashier, Accounts Department, Apapa Quays or Ports Harcourt Quays, as the case may be.

4. The completed Form of Tender should be returned to the Secretary, Nigerian Ports Authority, 216, Broad Street, Lagos, in a sealed envelope marked "CONFIDENTIAL - TENDER FOR SCRAP MATERIALS" as to reach him not later than 4 p.m. on Friday 25th January, 1963.

5 The successful tenderer, upon being advised of the acceptance of his tender, will be required to pay for the scrap materials within 7 days of the date of notification of such acceptance, and also to cut (where necessary) and remove the scrap materials at his own expense within 7 days of the date of payment of the purchase price The deposit of £20 will not be refunded in any event to any tenderer who fails to pay for, and remove the materials as stipulated.

6 The Authority reserves the right to resell any materials not removed by the purchaser after 7 days of payment of the purchase price, and such purchaser shall fo feit such payment in the event of such non-removal.

7 The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

N.P.A. Notice No. 849
7th January 1963

BAYO KEHINDE,
Secretary to the Authority


# Eleti–Ofe D'araba

# Nihin Lohun ·Ati Nibi Gbogbo

LATI OWO AYILUKA

## Adedoyin

Mo gbọ wipe Ọgbẹni Adeoye Adisa, Minisita tuntun ti o wa fun eto ikede Ijọba ni Ibadan ni awọn fẹ da ẸWU-GAWU fun ọrẹ mi Ọmọba Adeleke Adedoyin, alaga ile Igbimọ aṣofin ni Ipinlẹ Iwọ Orun fun iwa alaigbọran ti o fi igba kan hu si Oloye S.L.Akintọla, tiṣe Olotu Ijọba Ipinlẹ na lori wipe "Ade" kọ lati pe ipade igbimọ awọn aṣofin na ki rogbodiyan to de.

## "Seriki Tulasi"

Adeoye Adisa ni kinni kan ni on fẹ ki "Seriki Tulasi" mọ, iyẹn ni wipe Ijọba Akintọla ton pẹlu Fani—Kayọde ko ni gba gbẹrẹ rara fun ẹnikan, ko ba ṣe awọn aṣofin tabi awọn awọn akọwe irohin ni. Adisa ni ẹnikẹni ti o ba tafelefele awọn yio fi kele gbee. Mo jẹri Ade "Seriki Tulasi" paapa ko gba g b ẹ r ẹ. Boya ko to to iwọn nkan bi oṣu meji si igbayi gbogbo rẹ a ti rọ loju olukuluk wa yio mọ ibiti a nlọ nipa Ijọba Ibadan tuntun yi.

## ỌBA ALAKE

Nwọn ni ọba ko ku Ọba ko jẹ; mo gbọ wipe gbara ti ọba Alake Ademọla Keji ti waja ni awọn ti o fẹ bọ si ipo rẹ ti ndu ori aga na, awọn bi idile Luwaji, Larun ati Okikilu. O fẹ dabi ẹni wipe gbogbo awọn ti nwọn wipe awọn ni Ọba Alake tun yi kan ni mo mọ lọkọkan. Mo mọ Ọgbẹni wa Abiọla Jacob ti gbogbo wa ma npe adape oruko rẹ ni "Lisabi" ni Amunigun ri ni Ibadan, mo si mọ Adebọ Okukẹnu, mo mọ Ọmọ'ba Samuel Gbadebọ bi ẹniti o mọ owo, Gbogbo wa pẹlu "SAG" ni a jọ ma nṣere pọ l'Ake nigba atijọ. Iyoku di ọsẹ ti mbọ.


Advert. N0. 8.

## Federation Of Nigeria Fourth Development Loan

The Central Bank of Nigeria has been authorised by the Federal Minister of Finance to raise funds within Nigeria by the issue of £15 Million registered Stock in February, 1963. The Stocks to be issued will be:-

1. £2 Million 5o/o Federation of Nigeria Fourth Development Stock 1968-to be repaid in full on 5th August, 1968.
2. £3½Million 51/4o/oFederation of Nigeria Founrth Development Stock 1972-to be repaid in full on 5th August, 1972.
3. £10 Million 53/4o/o Federation of Nigeria Fourth Development Srock 1987-to be repaid in full on 5th August, 1987.

The three Stocks will be issued at par in multiples of £10 and applications will be accepted at banks throughout Nigeria or at the offices of the Central Bank in Lagos and Kano up to the close of business on 5th February, 1963.

Prospectuses, which contain full inf rmation, and application forms, may be obtained from banks and Stockbrokers or at the Central Bank's offices in Lagos and Kano up to the close of business on 5th February 1963.

W. A. TIBBLES,
GENERAL MANAGER.

Central Bank of Nigeria.
January, 1963.




**Ninu aworan yi ni e o tiri a w o n odomode ilu Oyinbo ti nwon ba oko ofurufu wa si ile Nigeria lati wa ran dokita alanu lowo ninu ise re, awon oniranlowo na ni nwon nko okutu kuro ni papa gbalasa kan leti ilu Sokoto nibiti oko ofurufu dokita na yio gbe ma ba ile si.**


**Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Eleti–Ofe Losose**

HINDU SANKARA'S
Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

Enclose 4/- money order by Air Mail for Catalogues and Literature.

HINDU SANKARA, 20 Montpelier Row, Blackheath, London, S.E.3, England

# Awon Ara Idumota Si Mosalasi Tuntun

EKO—Laipẹ yi ni awọn ara Idumọta si Mọsalasi wọn ti nwọn ṣẹṣẹ tun kọ ni John Street (Oni-tolotolo) l'Eko, awọn ti o ṣe alaga eto Mọsalasi na ni Alhaji Y Boshali Oloye Onisẹmọ, Tawaliu Bello, Alhaja Barikisu Ọlọjọ ati Iyaafin Ebudọla. Lemọmu gbogbo ilu, Alhaji Ibrahim, ni o kọ ṣe adura ki nwọn to ṣi Mọsalasi na, lẹhin eyi Alhaji Lemọmu Aliu Popoọla sọrọ ni ṣoki nipa Mọsalaṣi na.

Ọgbẹni Y.B. Gaji tiṣe akọwe awọn igbimọ Mọṣalaṣi na ni o fi gbogbo awọn ti o ṣe alaga lọkunrin ati lobinrin han gbogbo awọn janmọ lọjọ na ki Lọya Arẹmu Kọtun ("K.K"). to ka iwe-eyẹ ọjọ na si etigbọ gbogbo enia. Bi Lọya Kọtun ti ka iwe-ẹyẹ na tan ni nwọn ba pe alaga pẹlu Lemọmu gbogbo ilu ki o wa ṣi Mọṣalaṣi na.

Ẹyẹ ọjọ na peleke fun awọn ara Idumọta. Gbogbo awọn enia pataki-pataki ti nwọn fi iwe pe si bi ẹyẹ ṣiṣi Mọṣalasi na ni nwọn wa sibẹ, awọn bi Alhaji D.M. Giwa, W Elias, S. Giwa M.A Tijani, B. Hakeem, Ọgbẹni Aliu Williams, L. L. Alebiosu, T. Adeniyi, Yusufu Giwa, Ahmed Debs, L.L Alebioṣu, K. Jishi, A.B Ajala, Alhaji Tamimu Kasumu, R O Gbajumọ Y. Davies, Shopẹyin, L.L Ọlalẹye, Liadi Aromashodu Alufa Ayinla Oniiotolo, Gbada Ekelojuoti, J T Gbajumọ, Alhaja M Ashorobi Iyaafin Ayọ Agoro, Saratu Davies, Abibatu Abina, Nusirata Davies ati ọpọlọpọ awọn enia.

# Oro Alake

## (O bere loju ewe keta)

ti nwọn ko de ni ilu Oyinbo na ti nwọn lọ. Bi ẹ ba ri aworan aṣọ ti nwọn wọ sara lọjọti nwọn nlọ fi oju kan Ọba ilu Oyinbo ti o wa lori oye ninu agbala rẹ ti nwọn npe ni Buckingham Palace ni London lọjọ na lọhun, wa gbadun fun un.

Lọjọ ti nwọn pada silẹ yi awọn ọmọ Ẹgba ti o wa l'Eko nibiti nwọn kọ gunlẹ si ṣe aṣẹyẹ ẸKU ABỌ ti o larinrin fun wọn; awọn ti Abẹokuta ni kinni o ṣubu lu awọn. Awọn na fi ile pọn ọti nwọn tun f'ọna roka; nwọn ro aṣọ, awọn ọkunrin si wọ ẹwu aran Busun-Ọba lati ki Ọba wọn ku abọ.

# Ero Iwonle

**Awon Egbe onisowo Gesi kan sese gbe ero iwonle kan jade ti owo re ko po rara lati ra. Ko si ise ile wiwon ti nwon ko le lo ero yi fun. Nwon de ero na mo ori igi elese meta ti o se gbe kakaki.**


## E Ma Polowo Oja Yin

Sinu iwe irohin ELETI ỌFẸ

ni Ọsọsẹ ki ẹ si ma ka iwe na nigbagbogbo

Kọwe ipolowo Ọja rẹ si

Olotu,

Eleti-Ọfẹ
28 Kọsọkọ St.
LAGOS




## Coker Commission :

# Awo And His Men To Refund £85,000

CHIEF Obafemi Awolowo, Leader of the Action Group, Chief Akinola Maja, Chief T. A. Doherty, Mr R. A. Allison, Chief Shonibare " and others" are to refund the £850,000 paid to the National Investment Properties Company by the Western Nigeria Goverment for the purchase of Moba Land.

The Commissioners who investigated the affairs of six Corprations in Western Nigeria ruled in their report which was published recently.

The Commissin hed found in the section of its report dealing with the Western Nigeria Housing Corporation, that a few days after payment, the amount was paid over to Chief Lenlehin for the Action Group.

The Commission found:

(1) that this Corporation, which was established for the purpose of increasing the availability in the Western Region of dwelling houses to members of the public and of industrial estates for purpose of industry, was doing useful work;

(11) the it was wrong of the members of the Corporation to have resolved to grant loans to themselves at 5 per cent interest instead of the 6 per cent payable on building loans made to Corporation staff and the 7 per cent charged to members of the public;

(111) that the Corporation's reasonable policy of "one man, one plot" had been abused by certain individuals, chiefly Mr. Alfred Rewane, who had acquired an excess of three plots, and

(IV) that the acquisition of the Moba land was highly irregular and indeed fraudulent.

ACQUISITION OF MOBA LAND :-

The commission found:-

(1) that the Moba land was first purchased by Dr. Maja and Chief Doherty under a conveyance dated October 10, 1958, for £11,000 from the Onikoyi family who were the original owners of the land under customary law.

Six weeks thereafter, the land was sold under a deed of conveyance dated Novenber 23, 1958 to Mr. R. A. Allison for £150,000 some eight onths thereafter, the same land was sold to the National Investment and Properties Conmpany Limited for over £718,000 under a conveyance dated July 4 1959;

(11) that at the request of the Western Nigeria Housing Corporation the Regional Ministry of Lands and Housing decided to acquire the whole of Moba village land including the portionsold to the National Investment and Properties Company Limited, and instructed Messrs Gleave and Fox, who had earlier been retained for the same purpose by the National Investment and Properties Company Limited to value it;

(111) that this firm put a value of £850,000 on the National Investment and Properties Company Limited interest in Moba on certain conditions, but without seeing that those conditions were satisfied, the Regional Government paid this amount to the National Investment and Properties Company Limited.


## NIGERIAN PORTS AUTHORITY

### TENDER FOR SUPPLY OF LORRY TRANSPORT

Tenders are invited from lorry transport contractors normally operating in Port Harcourt for carrying out the following works for the period of one year:-

(a) conveying produce on a tonnage basis by suitable flat lorries from Arcon Sheds and Warehouses in Port Harcourt Quay to ships' side within the area of the Quay or from ships' side to the Arcon Sheds and Warehouses within the same area;

(b) the supply of suitable vehicles up to and including 10 tons capacity on a time basis for work either within or outside the quay area other than for the purpose covered in (a) above.

2. Requisitions for lorries will depend on the needs of the Dock Superintendent which will fluctuate considerably from day-to-day but contractors must be able to meet requirements at all times.

3. No labour will be required of the contractor to load or off-load produce and this fact must be borne in mind when quoting rates.

4. Contractors interested should apply to the undersigned or to the Port Manager, Nigerian Ports Authority, Port Harcourt, for the Form of Tender including the draft of the Agreement which will be entered into.

5. A deposit of £10 is required to be made by each contractor wishing to tender before the Form of Tender can be issued. Such deposit should be made to the Authority's Cashier either at Apapa Quays, Lagos, or at Port Harcourt Quay, Port Harcourt and the receipt presented to either the undersigned or to the Port Manager, Port Harcourt, to enable the Form of Tender to be issued. Deposits are returnable only on receipt of a bona fide tender.

6. All tenders irrespective of where the form has been obtained must be enclosed in sealed envelopes, marked "CONFIDENTIAL-TENDER FOR LORRY TRANSPORT, PORT HARCOURT" and must be submitted to the Secretary to the Authority, 216, Broad Street, Lagos, to reach him not later than 4 p.m. on 31st day of January 1963.

The Authority does not bind itself to accept the loweet or any tender.

BAYO KEHINDE,
Secretary to the Authority.

N.P.A. Notice No. 850.
8th January, 1963.



# Read

## And Advertise

### In ELETI-OFE.

## Awon Omo Iya Bia... Je Oju Won Ku Bamu-bamu

(O tẹsiwaju lati loju ewe kini)

Lọ... awọn ara adugbo ti ranṣẹ si awọn obi wọn nibiti nwọn gbe lọ ba wọn ṣe iyawo pe awọn ọmọ ti nwọn fi silẹnilẹ ti ku. Ọlọrun ma jẹ ki a rin lọjọ ti ebi mpa'na.

## Ijoba Apapose Fe Fi Owo Ra Owo

EKO—Irohin nla kan ti a gbọ loru ana ni wipe Ijọba Apapọṣe l'Eko fẹ na owo gọbọyi kan lati fi ra owo ẹyọ owo-atijọ lọwọ awọn ti owo na ba ku lọwọ wọn jake-jado ilẹ Nigeria.

Alaye yi jade lẹnu Ọgbẹni T O Benson tiṣe Minisita alamojuto eto ikede; o ni awọn Olotu Ijọba Apapọṣe ti jiroro lori ọrọ awọn ara ilu ti nwọn wa ni ilu Oke, ni oko awọn Ibo ati Hausa ti nwọn nkigbe wipe owo-atijọ na si kun ọwọ awọn jaburata ti nwọn ko gba wọn mọ lọwọ awọn nitoripe banki ti awọn le parọ wọn iinne si awọn.

Nitori eyi Ijọba yio na ẹgba mẹdọgọọn pọnun (£50,000) lori iparọ awọn owo na fun oṣu mẹta gbako si, ...wọn si ti pa laṣẹ fun gbogbo awọn akọwe ile-owo Ijọba kakiri wipe nwọn le fi awọn owo-atijọ na san owo-ori (tax) tabi gbese miran ti enia ba jẹ Ijọba titi di ipari oṣu March.


# Eleti-Ofe D'araba




Driving any car with the three pointed star you will experience that special joy shared by Mercedes-Benz enthusiasts all over the world: The joy in perfection, in superb craftsmanship in every detail and in lasting value, in discreet elegance and in the reassuring knowledge of driving in comfort and safety at all times, anywhere.

MERCEDES-BENZ

# LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS (E.B.) . IBADAN . KANO . KADUNA . JOS . PORT-HACOURT . ABA

Sub--Distributors :

## ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN . CITY . ONISHA . ABA


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Co., mpany, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370 EDITOR Olotu ỌLA ỌNATADE